# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

OṢÙ KẸ́SÀN, ỌDÚN 2022

Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́

## OSÙ KẸ́SÀN 2022
## GÒLÍÁTÌ ÀTI SENNAKÉRUBÙ MI GBỌ̀DỌ̀ KÚ

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

## MO KẸ́SẸ̀ MI LÉ JÉSÙ

**1.** Mo kẹ́sẹ̀ mi lé Jésù,
Ọ̀dágùtàn mímọ́,
Ó ru gbogbo ẹrù mi,
Ó sọ mí d'omìnìra
Mo ru ẹ̀bi mi tọ̀ wá
K'Ó wẹ èrí mi nù,
K'ẹ́jẹ̀ Rẹ iyebíye
Lè so mí di mímọ́.

2. Mo k'áìní mi lé Jésù,
Tìrẹ l'ohun gbogbo;
O w'àrùn mi gbogbo sàn,
O r'ẹ̀mí mi padà,
Mo kọ ibànújẹ́ mi,
Ẹ̀rù àt'àníyàn
Lé Jésù, Ó sì gbà mí,
Ó gba ìrora mi.

3. Mo gbọ́kàn mi lé Jésù,
Ọkàn àrẹ́ mi yì;
Ọw'ọ́tùn Rẹ̀ gbá mi mú,
Mo simi l'áyà Rẹ̀,
Mo fẹ́ orúkọ Jésù
Ìmánúélì, Kríst'
Bí òrún dídùn yíká
Ní orúkọ Rẹ̀ jẹ́

4. Mo fẹ́ kí nrí bí Jésù,
Ní rẹ̀lẹ̀ at'ìfẹ́;
Mo fẹ́ kí nrí bí Jésù,
Ọmọ mímọ́ Bàbá;
Mo fẹ kí mbá Jésù gbé
Lárìn ẹgbẹ́ mímó,
Kí nkọrin ìyìn títí,
Orin t'ángẹ́lì nkọ

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo àsọtẹ́lẹ̀ òdì fún ayànmọ́ mi, kí n tó kúrò níbí lónì, yóò padà sọ́dọ̀ ẹni tó rán a, ní orúkọ Jésù.
2. Lónì, gbogbo ètò sátánì fún ayé mi, yóò wó lulẹ̀, yóò sì kú, nípa agbára tó n bẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, ní orúkọ Jésù.
3. Agbára láti mú àwọn àlá ayànmọ́ mi sẹ, mo wà níbí lónì, gbé ayé mi wọ̀ nípa iná. ní orúkọ Jésù.
4. Gbogbo agbára òkùnkùn tó gba iṣẹ́ ibi ṣe láti dènà ìfarahàn àwọn ibùkún mi níbí lónì, gba àrá Ọlọ́run, kosì kú, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo agbára, tí wọ́n yàn láti mú ìlọ́ra bá itẹ̀síwáju mi, lónì, mo pín ayé mi níyà kúrò lọ́dọ̀ rẹ, kú, ní orúkọ Jésù.
6. Àwọn ibùkún tuntun, ògo tuntun, àlàjá tuntun, àwọn ẹ̀rí tuntun, ògo tuntun, mo wà lárọ̀wọ́tó, gbé mi wọ̀ báyìí, ní orúkọ Jésù.
7. Gbogbo ẹ̀jẹ̀ búburú, tó n sọ̀rọ̀ lòdì sí ayànmọ́ mi, nípa agbára tó n bẹ nínú ẹ̀jẹ̀ Jésù, látòní lọ, o kò tún ní sọ̀rọ̀ mọ́, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ**

**Ìjẹ́wọ́: Orin Dáfídì 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Ìsun agọ̀ tó n ṣàn nínú mi, gbẹ dànù nípa iná, ní orúkọ Jésù.
4. Awakọ̀ ìpadàsẹ́yìn, tó n ṣàkóso ọkọ̀ itẹ̀síwájú mi, gba ìṣínípò, ní orúkọ Jésù.
5. Ònfà ìkùnà, tó n so mí pọ̀ mọ́ onírúrú ipá ìkùnà, sọ agbára rẹ nù, ní orúkọ Jésù.
6. Ọ̀tá tó léwu, ipa ọ̀nà mi kì í ṣe ọ̀nà rẹ, gbá dànù kúrò lọ́nà mi, ní orúkọ Jésù.
7. Ìwọ ẹni ẹ̀mí mi, gba irànlọ́wọ́ atòkèwá láti kúrò nínú gbogbo ipò tó léwu tí wọ́n dè ọ́ mọ́, ní orúkọ Jésù.

# ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**Lúkù 10:19:** Kíyèsi i, èmi fún nyín ní àṣẹ láti tẹ ejò àti àkekè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohùnkan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa-nyín-lára.

**2 Pétérù 2:9:** Olúwa mọ bí a tí íyọ àwọn ẹni ìwà-bí Ọlọ́run kúrò nínú ìdanwò àti bí a tí ìpa àwọn àláìṣòtó tí à njẹ níyà mọ́ dé ọjọ́ ìdájọ́:

**Ìsàíàh 54:14:** Nínú òdodo li a ó fi ìdí rẹ múlẹ̀: ìwọ ó jìnà sí ìnira; nítorí ìwọ kì yóò bẹ̀rù: àti sí ìfòyà, nítorí kì yóò súnmọ́ ọ.

**Jóélì 2:25-26:** Èmi ó sì mú ọdún wọnnì padà fún nyín wá, èyí tí eṣú òn irú kòkòrò jewéjewé, àti irú kòkòrò kejì, àti irú kòkòrò jewéjewé míràn ti fi jẹ. Àwọn ogun nlá mi tí mo rán sárín nyín. Ẹ̀yin ó sì jẹun lọ́pọ̀lọpọ̀, ẹ ó sì yọ̀, ẹ ó sì yin orúkọ Ọlọ́run nyín, ẹnití ó fi ìyanu bá nyín lò; ojú kì yóò sì tì àwọn ènìyàn mi láí.

**2 Tímótéù 1:7:** Nítorípé Ọlọ́run kó fùn wa ní ẹ̀mi ìbẹ̀rú bíkòṣe ti agbára, àti ti ìfẹ́, àti ti ọkàn tí ó yè koro.

**Fílíppì 4:13:** Èmi lè ṣe ohun gbogbo nínú Krístì ẹnití nfi agbára fún mi.

**Lúkù 10:19:** Kíyèsi i, èmi fún nyín ní àṣẹ láti tẹ ejò àti àkekè mọ́lẹ̀, àti lórí gbogbo agbára ọ̀tá: kò sì sí ohùnkan bí ó ti wù kí ó ṣe, tí yóò pa-nyín-lára.

**Éfésù 6:10:** Lákotán ará mi, ẹ jẹ́ alágbára nínú Olúwa, àti nínú agbára ipá rẹ.

**Orin Dáfídì 40:13:** Kí ó wù Ọ́, Olúwa, láti gbà mí: Olúwa, yára láti ràn mí lọ́wọ́.
**Obadíàh 1:17:** Ṣùgbọ́n ìgbàlà yóò wà lórí òkè Síónì, yóò sì jẹ́ mímọ́, àwọn ará ilé Jákọ́bù yóò sì ní ìní wọn.

**3 Jòhánnù 2:** Olùfẹ́, èmi n gbàdúrà pé nínú ohun gbogbo, kí ó lè ma dára fún ọ, kí o sì ma wà ní ìlera, àní bí ó ti dára fún ọkàn rẹ.

**Fílíppì 1:6:** Ohun kan yì ṣá dá mi lójú, pé ẹnití ó ti bẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ rere nínú nyín, yóò ṣe àṣepé rẹ̀ títí fi di ọjọ́ Jésù Krístì.

**Jòhánnù 10:10:** Olè kì íwá bíkòṣe láti jalè, àti láti pa, àti láti parun; èmi wá kí nwọ́n lè ní ìyè, àní kí wọ́n lè ní i lọ́pọ̀lọpọ̀.

**Isaiah 53:4-5:** Lótọ̀, Ó ti ru ìbìnújẹ́ wa, Ó sì gbé ìkánú wa lọ; ṣùgbọ́n àwa kà á sí bí ẹnití a nà, tí a lù láti ọ̀dọ̀ Ọlọ́run, tí a sì pọn lójú. Ṣùgbọ́n a ṣa a lí ọgbẹ́ nítorí ìrékọjá wa, a pá á lí ara nítorí aìṣedédé wa; inà alàfíà wá wà lára rẹ̀, àti nípa inà rẹ̀ li a fi mú wa lára dá.